## Owe

Ma ṣe ıẹki ọwọ ọtun rẹ mọ ohun ti ọwọ osi rẹ nṣe.
Ẹnikẹni ti o ba pa ahọn rẹ mọ, yio pa ọkan rẹ mọ kuro ninu iyọnu.
Ra otitọ ki o si di mọ aiye rẹ kikan.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ „DE„ OKUNKUN PARADA.



## Wanted

Advance Apprentice Compositors
Apply in Person:- POPULAR PRESS
6, Ojo Road,
Odu-aborẹ Mushin.



VOL. V No. 322 MONDAY MARCH 26 — APRIL 1 1962 KỌBỌ MEJI (2d)


# A ko gba ki Ijọba da ṣiṣe Ẹyọ duro, ki o ma ba wun wa bi itọ ti nwun Adiẹ

Eko:- Opo awon e ni a lo ti nfi enu so isokuso wipe ki Ijoba da ere Adamuorisa duro ki won ma se ni l u Eko mo.

Ere Eyo je e y i t i o se pataki julo ninu awon ere Ibile Eko, ti o ye ki Ijoba se itoju re ki o mase pare.

Bayi ni a nṣe nilu ẹni, eriwọ ibomiran, ẹnikẹni ti mọ wipe bata wiwọ, ati fila dide ni eriwọ ti enia ko gbọdọ ṣe niwaju Ẹyọ gbogbo awọn ọmọ I b i l ẹ lo mọ eyi bẹ.

Nitorina, ki awọn ajeji to ba ri pe on ko le ṣe ki on maṣe de fila tabi ki on maṣe wọ bata, ki o joko ninu i l e rẹ, ki o maṣe wa woran. Owe Yoruba kan sọ bayi pe, ofofo alejo bẹ la ti nṣe ara wa, o di gba melo ti enia nsọ fun Gesi pe ki nwọn maṣe kareta mọ (Carnival) tabi I b o pe ki wọn ma gbe Egungun?.

Awọn ere meji ti a ni nilu Eko ni ere Adamuoriṣa ati e r e Ẹlẹgba, a fi eyiyi ke si ẹnyin ọmọ ilu Eko lati dide si ọrọ yi, ki Ijọba maṣe pa ere Ẹyọ rẹ. Awọn Aguda ko pa ere Bọnfi rẹ. Imale ko pa Rabiu Lawal rẹ, Ijo Kiriyo ko si pa ere Keresimesi rẹ, Ẹ ba wa moju to ọrọ na.

# Ẹja di Enia

EKO:- Ni dede agogo mẹwa abọ arọ Ọjọ'ru tiṣe ọjọ konkandinlogun oṣu kẹta ọdun yi ni a gbọ irohin lati ebute ẹhingbẹti pe ẹja di enia, Bi ọkunrin Ọ d ẹ apẹja kan ti ndẹ awo rẹ ni ebute ti o nfa awọn rẹ mọra, ni o ri pe o wiwo, o si lero pe ẹja nla ni awọn na gbe, o si pe awọn Ọdẹ Apẹja ẹlẹgbẹ rẹ lati ba fa gun oke, bi wọn ti nfa gun oke tan, ni o ba di enia, ọmọ ọkunrin gende Ọlọrun ti a lero pe o ti ku sinu omi lọjọ pipẹ, bi nwọn si ti ri oku yi bẹ, ni gbogbo wọn tuka pẹrẹ n i t o r i ẹru ba wọn pupọ lati ri pe enia lo wa ninu awọn na ti wọn lero pe ẹja nla ni.

A gbọ pe gbogbo enia ti o nkọja lọ nigba na ti o si ri awọn Apẹja wọnyi ti wọn sure gun oke, ni o sare lọ sibẹ, lati lọ wo ohun ti o ṣẹlẹ si nwọn. Awọn Ọlọpa sọ fun Onirohin wa kan pe, boya ọkunrin na le jẹ ẹniti wọn wa sọ pe o ja somi nigbati o fẹ ṣe ẹiyẹ ninu ọkọ Katilini ni ọjọ kọkandilogun oṣu kẹta ọdun yi 19th March 1962.

Gẹgẹ bi a ti gbọ, nwọn ni oku omi na wọ ẹwu alakọwe, eyi ṣẹti, o si wọ sokoto kaki penpe, o da gba to ẹni ọgbọn ọdun, titi di isisiyi a koiti ri ẹnikẹni ko sọ pe enia on ni oku omi na, tabi ẹniti o ni on mọ ile ati ọna rẹ. Ẹja ni Ọdẹ dẹ awọn fun, ṣugbọn nigbati o gunlẹ o di enia, Ẹja nla lo nfi ori la ibu.

IROHIN OJIJI:- Gẹgẹbi ẹ o ti ri ka ninu oju ewe kẹjọ iwe wa ọsẹ yi nipa irohin pe Bishop Howells da Alufa Dọkita Lukas duro.

Irohin ojiji kan tẹ wa lọwọ pe Alufa na Ẹni-Ọwọ Dọkita Lukas na si ti fi iṣẹ Alufa silẹ larapa ẹsun ti awọn ijọ rẹ fi kan. Ki si ṣe Alufa mọ fun Ijọ Bẹrẹfutu, o ti ju ọwọ silẹ.

## Kabo o Ol a ilu Ilesha



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Alaiyeluwa Ọba Biladu K e j i Ọwa Ilesha, nigbati o dakan wa lati igboro ilu I l e s h a lati wa bẹ awọn Alasẹ Oyinbo U. A. C. wo, nitoripe nibọ lo ti nṣiṣẹ ki o to wa Joye Ọba.

Ọba yi ni o jẹ Oye Baba-ẹgbẹ fun awọn Igbimọ Lọba-Lọba, on ni a nwo ti o joko ti o si nrẹrin larin meji awọn obinrin.

# ỌRỌ OLOTU

## O KARE SADAUNA

A gba fun ọ, ọmọ Ọba Sadauna, Olori Ijọba ilẹ Hausa. Ni ọsẹ to kọja, o fi han gbangba pe Iwọ Orun nikan ko lo ṣetan ati ṣe ara wọn.

O kede ipinnu Ijọba rẹ pe idamẹwa owo Oṣelu kọkan ni awọn yio ge. Ki iṣe Oṣelu nikan, gbogbo awọn Oṣiṣẹ ti o ngbowo nla-nla ni owo wọn yio dinku.

Ọlọla Sadauna si tun gbe ọmọ ilẹ Hausa si ipo Oyinbo nibi iṣẹ Ijọba. Gẹgẹ bi a ṣe sọ ni ọsẹ tokọja pe, Ọdun titun ti de. Iwa titun si ti ba wọle.

## Sugbon e je ka ronu.

Ṣugbọn bi iba ṣe ma dun to, anu ṣe ni pe onikaluku ni o nja fun Ipinlẹ rẹ, o si da bi ẹnipe ifẹ Naijiria gẹgẹ bi ilẹ kan jinna si wa. Ni ọsẹ to kọja ninu ile iṣofin ilẹ Hausa, nibiti Ọlọla Sadauna ti nṣe olori ni ọmọ Hausa kan, ọmọ ẹgbẹ N. P. C. ni ki nwọn le gbogbo ẹniti ki iṣe Hausa kuro ninu iṣẹ ni ilẹ Hausa.

Anu ṣe ni lati gbọ eyi ni akoko ti a nrojọ iya ti a gbọ pe nwọn nfi jẹ ọmọ Naijiria ni fenando Po. Ọrọ wo ni a wa fẹ sọ nigbati o jẹ wipe ninu ilẹ wa, a ko le mu ara wa mọra. Ṣugbọn nigbati a ba ranti pe ẹniti o sọrọ yi ni ile Iṣofin ilẹ Hausa ọmọ ẹgbẹ ti o nṣe Ijọba gbogbogbo ilẹ Naijiria ni, aiya wa yẹ ki o ja. Nitoripe bi o ba jẹ ohun ti o wa ni ọkan ẹgbẹ rẹ ni o sọ jade, bi o ba pẹ o daju pe nwọn ko tilẹ ni fẹ ki ẹnikẹni ti ki iṣe ọmọ Hausa tabi ti ki iṣe ọmọ ẹgbẹ N. P. C. ri iṣẹ labẹ Ijọba gbogbogbo mọ.

Ko si ẹniti ko fẹ ki ilẹ Hausa ma fun awọn ọmọ wọn ni ilọsiwaju tabi iṣẹ Ijọba, ṣugbọn eyi ko ni ki nwọn le awọn ọmọ Naijiria miran ti o ba nṣe iṣe daradara sọnu, ki nwọn ranti pe bi ọmọ Yoruba ati Ibo ṣe wa ni ilẹ Hausa bẹ ni ọmọ Hausa wa kakikiri.

## Nwon se adehun papo lati ma ba ara won sowo



Awọn ti a nwo ninu aworan oke yi ni Ọlọla Alhaji Bukar Dipcharima, ti iṣe aṣoju Ijọba Alapapọṣe ni ilu Eko fun idagba ṣoke iṣẹ owo ṣiṣe kakiri ilẹ Naijiria, ẹni keji ti o mbẹ ni ọwọ ọtun ni Ọgbẹni Frantisek Krayier, on ni aṣoju Ijọba Sekoslofakia fun awọn ilu okere

Awọn Alagba Ọlọla mejeji nwọnyi ba ara wọn ṣe adehun ki iṣẹ owo ṣiṣe, rira ati tita bẹrẹ larin ilẹ Naijiria ati ilẹ Sekoslofakia. Nisisiyi, adehun na ti duro, awọn mejeji si ntọwọ bọ iwe adehun na fun ra nwọn.

# Yẹyẹnatu!

## ONIYEYE EKO!

Yẹyẹnatu: Olotu ọrọ kan ni mo ma wa bere

Olotu: Ọrọ wo ni yẹn o, Yẹyẹnatu?

Yẹyẹnatu: Adedeji, aburo ọkọ mi.

Olotu: Ṣe eyi ti o wa ni Ibadan?

Yẹyẹnatu: Hẹn o! to wa ni Fasiti.

Olotu: Hẹnhẹn! kilo wi?

Yẹyẹnatu: O ransẹ pe on fẹ Joye ni Ibadan ni ọjọ mẹdogun.

Olotu: Oye kẹ, ṣe bi ki iṣe ọmọ Ibadan?

Yẹyẹnatu: O ni iṣẹ ati gboye ni on nkọ ni Fasiti.

Olotu: Ha! ha! ha!

Yẹyẹnatu: Nkan to npa mi lẹrin gan ni yẹn, mo ni iyẹn ni pe enia nkọ iṣẹ ati Joye? A ko ma gbọ pe Ijoye kan lọ fun iru ẹkọ bẹ nilẹ yi ri kẹ.

Olotu: Ha! ha! ha! Jọwọ ma pa mi o, Yẹyẹnatu

Yẹyẹnatu: Lotọ ni kẹ, ko ye mi ni, o ni Oye a sọ itan ni on fẹ jẹ. Bẹ bi enia fi omi si lẹnu yio ba nibẹ.

Olotu: O dara, duro ki nla ye ọ, ki iṣe iru oye bẹ ni. Ti enia ba kawe ti o ye koro, nwọn a da lọla, nwọn a fun ni iwe eri pẹlu, apele orukọ, eyi ni oye iwe.

Yẹyẹnatu: Hahẹn! ẹ ṣe. Nwọn ni ẹ wadi ohun gbogbo daju-daju.

## Oba Aiyetoro si Oja Obada

NI ỌJỌ KẸTADINLOGUN OṢU YI NI ALAIYELUWA ỌBA ONI, ỌBA AIYETORO NI EGBADO ṢI ỌJA ỌBADA NI IDI ẸMI.

Ninu ọrọ iwuri ti o fun ara ilu na, o bẹ wọn ki nwọn ma pa ofin Ijọba mọ, ki nwọn si ri pe awọn nsowọpọ fun ogo ilu

Oloye Akinlẹyẹ, alaga Kansulu Ẹgbado Ketu na sọrọ, o dupẹ lọwọ awọn Ọba ati Ijoye ti o wa nibẹ ati ni ipinlẹ wọn, o si bẹ wọn ki nwọn gbagbe ọrọ ana ki nwọn fi Imọ wọn ṣọkan fun ogo ilu wọn.

O dupẹ lọwọ awọn ara Ilu fun iru ifẹ ti nwọn fi ṣiṣẹ ọja na.

**Irohin Imole daraba**

# Ọlọla Oloye Fadayiro ṣe ajọdun ẹni adọta ọdun ( GOLDEN JUBILI )

Ibadan:- Irohin ta si wa leti wipe Oloye E. A. A. Fadayiro ti se Onirohin fun Ijoba Iwo Orun se Ajodun Golden Jubili.

Iyẹn ni wipe o goke agba o di ẹni adọta ọdun nile aiye lọjọ 18th March 1962.

Nilu Ilaro ni wọn ti ṣe isin fun ti Ajọdun na, ninu ile isin Christ Church, ni agogo mọkanla abọ ọjọ na. Ẹniti o si ṣe isin na ni Ọlọla, Ẹni ọ w ọ Alufa S. O. Odutọla ti iṣe Bishop ilu Ibadan, ati awọn Alufa miran ni o ṣe isọngbe rẹ, ati pe ni gẹrẹ ti nwọn pari isin na tan ni ase rẹpẹtẹ berẹ ninu gbọngan ile ẹgbẹ ti a npe ni Coronna H a l l ni Ilaro.

Iwọnyi ni iba i t a n ti a gbọ nipa Oloye Fadayiro Ni ọjọ 18th oṣu M a r c h 1962. ni a bi O l o y e yi, orukọ Baba rẹ ni Daddy Solomon O. Fadayiro ti iya rẹ njẹ Efunyanju Yewande o bẹrẹ ẹkọ rẹ ninu ile iwe Christ Churh ni Ilaro. Diẹ ninu awọn ti n w ọ n jijọ nkọwe lakoko na ni Oloye A. A. Laditan Erastus Ọtẹgbẹyẹ, Iyafin Onifade.

O bẹrẹ ẹkọ giga rẹ ninu ile ẹkọ Grammar School ni Eko lọdun 1925, nigbati o si di ọdun 1928, nwọn fun ni ẹbun ẹkọ ọlọfẹ lati lọ si Kings College ni Ekọ lọdun 1931 o lọ kọ iṣẹ iṣẹgun ti oyinbo ni Yaba Higher College, o si bẹrẹ iṣẹ labẹ Ijọba Oni b o d e (Customs & Excise) lọdun 1936:

Nigbati o kuro ni bode o bẹrẹ iṣẹ Ijọba labẹ Oyinbo Ajẹlẹ agba ni Oke Igbehin ni Abẹokuta.

Lati ihinyi lọ li o ti lọ bẹrẹ iṣẹ Iṣelu ni ileṣẹ P. R. O. ni Abẹokuta, on lo si nṣe olotu iwe Irohin awọn ọmọde kekeke, o nṣe irohin ni akoko ogun, o si nfun awọn e n i a ni aworan bi ogun ti nlọ si.

Nwọn fi jẹ o y e Apesin Iboro lati ọwọ Ọba Iboro Ilaro, o si tun joye Olori Apesin lati ọwọ Ọba Olu Ilaro, o jẹ ọkan ninu awọn igilẹhin ọgba ti o da Ẹgbado College silẹ.

Nwọn y a n a si Igbimọ lọdun 1956. Bayi ni Oloye Fadayiro ṣe kẹrẹ kẹrẹ o de ipo Minister of Information eyi ni Onirohin fun Ijọba Iwọ Orun.

---

## Omo titun jojolo kan da oko re lati orun wa

OWERRI:- Ọmọbinrin kan ti ko bimọ ri, ni a gbọ pe o bimọ ni a b u l e kan ti a npe ni Umunyiala ni ilẹ awọn ara Owerri, nigbati awọn aladugbo sare de ibẹ ti nwọn bẹrẹ gbe ọmọ titun na nilẹ lati lọ wẹ fun nwọn ri pe ọmọ na ti dako rẹ la ti ọrun ki o to wa si aiye.

Awọn obi ọmọ na sare lọ pe awọn aladugbo lati wa wo iru ọmọ abami ti wọn bi, nwọn tun ranṣẹ lọ pe Padi ati awọn Sister.

Padi so pe, afara ko ṣ ṣe ki awọn obi ọmọ na ma ṣe jafara lati fun ọmọ na ni orukọ.

---

## Ode to fe pa Lagido yinbon ba ara re o si ku

OGOJA:- Ọkunrin kan nilu Ogoja ti orukọ rẹ njẹ Gboṣe Atan, ti o nṣiṣẹ Ọdẹ on pẹlu awọn ọdẹ ẹlẹgbẹrẹ, ṣigun lo ba awọn Lagido ati Ọbọ ti o mba awọn nkan inu oko wọn jẹ.

Nigbati nwọn de ọhun, nwọn ri Ijimere nla kan ti o joko larin awọn ẹka Igi bi nwọn ba wipe ki nwọn yinbọn si Ijimere na nibiti o joko si, ibọn ko ni ba gẹgẹ bi nwọn ti fẹ.

Ibẹ ni Ọkunrin ti w ọ n npe ni Gbose Atan yi ba so okun mọ ibọn rẹ, o si gbe ti sara igi li o ba lọ sori igi Nigbati o de ori igi na tan, o j o k o, o ri wipe bi on ba yinbọn lati i b ẹ yio ba Ijimere na yio si pa ni apafọn. O wa b ẹ r ẹ si fa okun ti o fi so ibọn rẹ, aṣe ṣamọ-ṣamọ lori akọ ni ibọn na wa, nibiti o gbe nfa ibọn na bọ l o k e, bẹni ẹka igi kan ba fa oko ibọn, ọkunrin ọdẹ yi ni ibọn si ba, lo ba ja lulẹ lati ori igi..

---

## SEBOTIMO (APA KEWA)

Lati ọwọ:- BỌSẸDE OLUFUNMILAYỌ

Mo ki gbogbo ẹnyin onkawe mi jake jado pe ẹku ajabọ ọdun oluwa jẹki aṣe ọpọ ọdun ki nto ma ba itan mi lọ ngo fi awure kekere yi ta yin lọrẹ; Or agilinti, ọka baba, iwo ronjeje, igbado pupa, a o gun pọpọ a o po mọ ọṣẹ aladi a o ma fi wẹ (Ọfọ rẹ) agilinti ma jẹki nti ọka baba ma jẹ ki nbaje, iwerejeje ki tẹ loju ọmọde, ki ntẹ agba, larin ọka ni boromọ ngba ọla larin ọka ol boromo ngba iyi a o ma fi kanriokan ti un wẹ ti a ba pe tan ki o ri fun yin gẹgẹ bi ibere yin, Oju glass ni a o ko ọṣẹ na si.

IKỌ ỌBA ILU ANU MU NINI-OWO DE ẸNU BODE OGUN

Lẹhin ti Iranṣẹ ọba ilu anu ati Nini-Owo pora mọ Ọbabinrin na loju ta ni gbokbo wọn wa wariku won si dakẹ lọ gbadari. Ni ọbabinrin na dahun pe, ṣe ẹri ile aiye ti bi ẹ ko ri? o ti di ofin lati isisiyi lọ pe a ko ni ma gba awọn alejo laye lati ma wọ ilu wa mọ, gbogbo wọn si dahun wipe aṣẹ hun ki a ma fa ọrọ gun lọ titi Nini-Owo ba ara rẹ lọnu ibode Ogun. ṣugbọn ko ri Iranṣẹ Ọba Ilu Anu mọ, ojoko lẹru ọna o nwo koran.

Akiyesi:- Ẹoyin onkawe mi ẹ ma ṣe binu simi pe itan mi ọsẹ yi kuru pupọ aiko raye ni ti o ba di ọsẹ ti nbọ lagbara ẹo ma ka itan mi na ni ẹkunrẹrẹ Awure ijilẹ ti mo fun fun yin yẹn ẹ di mu dada o.

---


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI A NPE NI:-

## "UROXAL"



Fun Itoju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney-Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ehin didun eri ile tabi itọ-jijo enia, itọ ririn, rukuruku Pipọn tabi ririn, lakuregbe, Ibara di wiwo, orunku, ọwọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju aiko le gbe ara konkọn tabi kiakia didaji loru nigbakugba, ati orisirisi awọn asan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹbadan yi yio wo san lara rẹ ni kia kia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni Ilu Nigeria nitorine ṣọra ki awọn eleru tabi awọn Oni rọbirọbi ma ta orisi omiran ti ko ni lari fun ọ, mase gba a rara o! Owo rẹ jẹ Ṣile Mẹfa abọ 6/6d owo ọkọ ṣile meji abọ (2/6d) Bere Egbogi yi ni ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878
WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OṢHOGBO.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# EWI ASIKO

LATI ỌWỌ:- **Afolabi Olabimtan**

## Agbajọ ọwọ

**BI a ba wolu, Onilu la koko ki**
**Mo ki nyin, Olotu, e ma ku ati**
Ẹ ku ọwọ gbọrọ bi ọwọ aṣọ
Gbogbo Ọnkawe Imọlẹ, ẹ ma ku atijọ
Ẹ ku airini aibere ẹni.
Ọrọ kan nbẹ lọkan mi ti ko jẹ nmi
Naijiria ndi mẹta, aiya mi nja
Naijiria fẹ di mẹrin ara nta mi gidi.
Isowọpọ to jinna o to ọrun referefe
Ifẹ ara ẹni jinna o de aju-le Ọrun.
Ilara ko jẹ ka ni fẹ ilu
Ika ko jẹ ka tun fẹ Naijiria ilẹ wa.
A! Olotu aisaṣọ lọrun paka
O ma to apero gbogbo Mariwo
Iṣelu Naijiria, o su mi su.
Ṣe ẹnu ofo ni wọn fi nwa iṣọkan.
Irọ ni gbogbo nwọn npa.
Ẹni nde enia mọlẹ bi ewurẹ
Nitoripe ko ba ṣẹgbọ kan
Ẹni nsọ'nia donigbese
Nitori aidibo fun lagbaja
Ṣe isowọpọ lo nwa fun wa?
Bẹ agbajọ ọwọ la fi nsọya
Ajeje ọwọ kan ko gbẹru dori
Gbogbo ika ni Basi fi nṣẹgun
Ọmọ Naijiria
Mo ke titi nko rẹni kẹti
Mo yan yan nko rẹni kan
Mo bẹ Megida ko ma ta baba lọfa
Ẹ ba wa bẹ Diayin ko ro ẹhin ọla.

---

## Igbekele Olorun ko pani lebi

Obinrin opo kan wa ni igba lailai ti o ni awọn ọmọde kekere meji, ọkan jẹ Ọkunrin ekeji si jẹ Obinrin, eyi Ọkunrin ni ẹgbọn, o si jẹ ọmọ ọdun meje, aburo rẹ ti o jẹ obinrin jẹ ọmọ ọdun marun, oṣu kẹrin ti o bi eyi obinrin ni Ọkọ rẹ ku ko si ni ẹni kan ti o le ran lọwọ nipa awọn ọmọ na. Obinrin yi jẹ ẹniti ọkan rẹ gba Ọlọrun gbọ pupọ, lati kekere ni o si ti kọ awọn ọmọ rẹ mejeji lati ma gbadura si Ọlọrun ki nwọn si ma ni gbẹkẹle si Oluwa.

Ni ọjọ kan aisan kọlu Iya wọn yi, ko ṣi si onjẹ rara fun on ati awọn ọmọ rẹ lati jẹ, ebi npa a. Nigbati o ṣe eyi Ọmọkunrin pe aburo rẹ Obinrin pe ki o ka lọ nile Ọlọrun ti o wa nitosi, ki wọn lọ gbadura, awọn mejeji si lọ.

LATI ỌWỌ:—

**LATIFU BABALOLA**

Akọwe Agba ẹgbẹ Imọlẹ

Nigbati awọn ọmọde mejeji yi de ile Ọlọrun, wọn kunlẹ, wọn si fi tọkantọkan gbadura lai mọ pe ẹnikan wa pẹlu wọn ninu ile Ọlọrun na. ohun ti wọn nwi ni pe ebi npa awọn ati Iya ni ile, ara Iya awọn ko si tun ya, awọn si kere ju lati ri iṣẹ ṣe. Nitorina awọn mbẹ Ọlọrun pe ki o fun wọn ni onjẹ gẹgẹ bi o ti nfun ẹiyẹ oju Ọrun, ati ẹranko inu igbẹ. Adura yi mu wọn lọkan tobẹ ti omije fi ndа loju wọn, wọn si nsọrọ soke lohun rara.

Ọkunrin Olowo kan wa ninu ile Ọlọrun yi ni akona gan, o ngbadura ni kọrọ kan, o si gbọ gbogbo ohun awọn ọmọ na nwi, o rọra fi ara pamọ fun wọn titi nwọn fi jade, o si fi ọgbọn tẹle wọn lati mọ ile ti wọn yio wọ. Ọkunrin Ọlọrọ yi fi ọpọlọpọ onjẹ ransẹ si obinrin na ati awọn ọmọ rẹ, o si tọju rẹ lai fi ara han titi aisan rẹ fi fuyẹ patapata

Nitorina kiẹjẹki a ma ni igbẹkẹle Ọlọrun, ki a si ma kọ awọn ọmọ wa ni ọna ti o tọ ti o si yẹ, ki wọn si ma ni igbẹkẹle Ọlọrun, nigbati ara obinrin na da, o mba iṣẹ rẹ lọ, o si yin Oluwa logo fun ọna ara ti o fi pese onjẹ fun on ati awọn ọmọ rẹ nigbati o nṣe aisan.

---

## Owe Yoruba

Anju wọn ko ṣe wi lẹjọ, ija lara ko tan bọrọ. A pẹ ko to jẹun, ko ni jẹ ibajẹ. Asure tete ko ti oye jẹ, A rin gbẹrẹ ni yio mu oye dele

## Itan ore meji

Lati Owọ:- MICHAEL OYE FALOYE. (ILUDUN)

Inu mi yio dun bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye lati sọ Itan Ọrẹ meji sinu iwe rẹ oloyin mọmọ.

Nigba Iwase, awọn ọrẹ mejikan nbẹ ti wọn jẹ ọrẹ imulẹ ati ọrẹ ti o nbo ọrẹ laṣiti, ninu awọn ọrẹ mejeji yi, ọkan jẹ Akura, Ara ekeji pe dele, ti Ọlọrun ti yayi awọn mejeji to, ko si ẹni tomọ iyatọ larin awọn mejeji, nitori awọn mejeji jọ fẹ iyawo sọna ni, ti wọn si nṣe ẹtọ pẹlu iyawo wọn nigba to pẹ iyawo eyiti ararẹ pe lo kọkọ dagba oto gbe, awọn mejeji si parapọ, wọn gbe Iyawo yi aiye gbọ ọrun si mọ pẹlu, nigbati wọn se iyawo yitan, kopẹ pupọ ni Iyawo ti akuradagba, on na to gbe.

Nigbati wọn fi pe iyawo ti Akura to gbe awọn mejeji tun jijọ ro ọjọ totọ lati gbe iyawo na. Wọn si pinnu larin ara wọn pe bi wọn ti ṣeti iyawo eyi ti Ararẹpe bẹri awọn yio ṣe Takura, kamafọrọ na gun lọtiti wọn mu ọjọ igbeyawo lọ si ile ana, awọn ana papa ti mura Tori wọn ri bi igbeyawo ọrẹrẹ ti dun to, nigbati Akura ripe ọjọ igbeyawo on ku sidẹdẹ ibanujẹ de ba emirẹ o bẹrẹsi ro ohun ti asiri on ko fi ni tu ati wipe ti gbogbo fari on kofini wọ omi. Ẹnyin ara, ki Oluwa ko jọwọ majẹki fari wa wọ mi Amin.

Nigbati Akura ro ohun ti yio ṣe ti ko ri, ope ọrẹ rẹ osọ fun pe, asiko to ti asiri on yio tu wayi o, Ọrẹ rẹ si bere lọwọ rẹ pe torikinni Akuradama gbọ wipe on lowo lọwọ eyi ti koja on laiya lati jẹun ati lati lesọ ṣugbọn bi iyawọ bawọle ọkan to ku nko lati ọjọ ti awọn nba ọrẹ wọn tọ ẹnikan ko mọpe Akura nikeji eyiti Ara rẹpe, obere lọwọ Akura pe ero ni ọ'an to ku, ki Akura to fes omi tọ

WO IYOKU LOJU EWE KARUN

---

## Onisowo Basikulu Rali ni Onibara titun nile Tangayika



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni N. Kisom ara ilu Dodoma nilẹ Tanganyika, ni o ni a gbọ pe o kọkọ jẹ onibara awọn Oyinbo ti o nṣe kẹkẹ Basikulu on li ẹniti o si kọkọ mu kẹkẹ Rali de ilẹ Tanganyinka Iṣẹ Olukọ lo wa ṣe nilu Oyinbo, ki o to lọ gba Onibara Kẹkẹ Rali.

O BẸRẸ LATI OJU EWE KẸRIN

lojurẹ nigbati eyi ti Ararẹpe ripe ẹkun ni Akura nsun on na busẹkun lai ko mọ eyi ti Akura nsukunsi awọn mejeji sunkun tẹra wọn lọrun eyiti Ararẹpe sọfun Akura pe maberu gbogbo ohun to ba jẹ alebu ara fun ọ ni ki osọ bi Ọlọrun ba fẹ aṣeri ti awọn yoruba npe lasiri asiri na ko ni tu si aiye, Akura sọ ohun ti nba ninu jẹ nigbati eyiti ararẹpe ridi ọrọ yi o sọ fun Akura pe, mafoya, ma bẹru ohun toro na tobi pupọ, pẹlu aṣẹ Oluwa on yio bo asiri na ti ẹda kan ko ni mọ ayafi bi on ba ku ki iyawo na towọle ni on ko sọ.

Nigbati Akura ileri ọrẹrẹ yi, ọkan rẹ balẹ awọn mejeji bẹrẹsi damọran bawoni awa yio ṣeti iyawo ko fi ni mọ pe Akura ni sẹ eyiti ararẹpe, oni bi iyawo na ba wọle ti awọn enia rẹ bapadasile wọn, bi wọn ba suntan lalẹ Ọrẹmejeji yi sida asiko fun ara wọn pe eyiti Ararẹpe sọ fun akura pe on yio duro lẹhin ilẹkun ko rọra ṣi lẹkun koja de eyiti ararẹ peni on yi ọrọra wọle bi on ba si ti ṣe tan, on na yio ṣe bi ẹ ni pe on fẹ lọ nigbana ni Akura yio pada losu ti iyawo rẹ otun ṣe alaiye fun Akura pe boya iyawo leberepe kiloṣe to fi lọṣo de, ni gbakugba bayi on kosọfun iyawo pe latorọ bi on mu nkan yagbẹ lomu onlọ to bẹ wọn pari imọran wọn sibẹ.

Nigbati ọjọ igbeyawo pe awọn mejeji bẹrẹsi nawo bi ala ra eyiti ojẹpe iyawo akura yi tun dun ọtun ni oki ki eleyi ti ara rẹ pe lọ. Lọsẹ ti o mbọ ligbara Oluwa ẹ o ma ka eyi to ku ẹtọju kọbọ meji yin


## MOGBAYI COUGH MIXTURE

Mogbayi Cough Mixture jẹ Ogun Ikọ pataki ti a ṣe ni aṣẹpe lati wo awọn Ikọ oriṣiriṣi san ni kiakia. O dara fun Ikọ agbalagba ati Ikọ ọmọde bẹni o si tun dara fun Ikọ ọmọ ọwọ pẹlu.

O dara pupọ ju gbogbo ogun Ikọ yoku lọ. O dara fun awọn arun Ikọ wọnyi, Ikọ ti o ma nha enia ni ohun, Ikọ ti o ma npọn enia loju, Ikọ ti ki jẹ ki enia sun dada, Ikọ ti o ma ndun enia lẹgbẹ, Ikọ ti o ma nta enia ni aya, Ikọ ti o ma nfa Ẹfọri, Ikọ ti o ma nfa arẹ ba ara, Ikọ ti o nmu ki enia ma pọ ẹjẹ, ati awọn Aisan miran ti wọn somọ Ikọ bi aiperi, oyi etc.

Mogbayi Cough Mixture yi dara pupọ fun ẹnyin ti Ikọ nyọ lẹnu. Ẹ ma ṣe ṣahun fun alafia ara yin, alafia ni opin ọrọ ijafara ni ewu pupọ, tete lọ ra Igo kan. Mogbayi Cough Mixture, yio wa ni ile itaja Egbogi ti o wa ni adugbo rẹ, Igo kan rẹ jẹ 2/6d' arapọ rẹ jẹ 24/-.)




LILO RẸ:-

Ọmọ oṣu mẹta—Idaji ṣibi tii kan ni wakati mẹtamẹta
Ọmọ oṣu mẹta si mejila:- Ṣibi tii kan nigba mẹta lojojumọ
Ọmọ ọdun kan si mẹfa.- Ṣibi tii meji nigba mẹta lojumọ
Agbalagba............Ṣibi Imukọ kan nigba mẹta lojumọ

*Wholesale Distributors:-*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHER

6, Balogun Street West
Lagos Nigeria.
Phone 22515.

34, Docemu Street,
Lagos.
Phone 24247.



**Ema ka iwe Irohin Imole ni gbagbogbo ki e si ma polowo oja yin si nu re**


# Igbehin Olofofo ki dara

Lati Ọwọ:- WOLI KOGBEREGBE

Mo fẹ sọ fun yin wipe koyẹ lati ma ṣe ofofo fun ẹnikeji rẹ Olofofo fẹran lati ma da adugbo ru ija ni olofofo ma da silẹ kiri, nitorina ẹnyin ọrẹ mi ẹ maṣe ba olofofọ enia ṣe ọrẹ pọ Eke enia jẹ alariwo ati agidi ẹsẹ rẹ ki duro ni ile rẹ, Nisisiyi o jade, nisisiyi ọ wa ni igboro, o si mba ni ibi igun ile lati maṣe ofofo rẹ kiri Owe 7 Ẹsẹ 11, nitorina mo fẹ ki ẹ mọ wipe ofofo lonsọ enia di ẹni ọtẹ, ati ẹni abukun, ṣugbọn maṣe ba eke enia ṣe ọrẹ rara gba, eke ati ofofo ọmọiya kana ni awọn mejeji ẹnikẹni tio ba nba eke enia ṣe ọrẹ pọ yio gba itiju ati wahala Nitorina mo fẹ ki ẹmọ wipe oṣi ni baba eke aṣeju ni baba ẹṣẹ mo fẹ ki ẹmọ wipe ẹlẹri ki o lọ laijiya ẹniti ṣe eke yi o ṣegbe ohun rere ko yẹ fun aṣiwere, Owe 19, Ẹsẹ 9,



WOLI KOGBEREGBE

ẹ sa fun eke enia ati olo fofo enia nitoripe wọn fẹ da ija silẹ ti iwọ ba tẹle eke enia iwọ yio da ẹṣẹ ti ko ni tan lailai Ẹniti o fẹ ija o fẹ ẹṣẹ ẹniti o kọ ẹnu ẹnu ọna ile rẹ ga o nwa iparun ẹniti oni ayidayida ọkan ki o ri ire ati ẹniti o ni ahọn ọrọ meji yio bọ sinu ibi ẹniti o bi aṣiwere o bisinu ibanujẹ rẹ baba aṣiwere ko le ni ayọ Owe 17 Ẹsẹ 19 mo fẹ ki ẹ mọ pe lati ma Iju olofofo enia ki o ma ba gbe a aiye lọwọ ẹnyin obinrin ẹṣọra lati ma ṣe ofofo ara yin fun ọkọ yin nitori bi aṣiri olofofo tu itiju yio si de nigbati igi tan ina a ku bẹni igbati olofofo ko si ni ile ija a bẹ silẹ bi ẹnyin ti ni si ẹnyin ina ati igi sina bẹni enia onija lati da ija silẹ ọrọ olofofo da bi adindun nwọn a si wọ isalẹ inu lọ Owe 26 Ẹsẹ 20 maṣe ba olofofo gbe pọ ko ma ba doju ti ọ ẹjọwọ ẹnyin ọrẹ mi olofofo enia kan ki o lọ L. i ri itiju bẹ si ni ẹlẹṣẹ kan ki o la ija iwọ abanijẹ mura ẹsan nbọ kankan lati sin fun yin olukuluku gẹgẹbi iṣẹ rẹ yi o ti ri ati gẹgẹ bi abanijẹ rẹ ṣugbọn mo fẹ ki ẹ mọ wipe egbe ni fun abanijẹ ti a ko ba ọ jẹ nigbati iwọ ba dẹkun a o ba ọ jẹ kanlẹ patapata ti ki yi o ni atunṣe mọ rara ISIAH 33 Ẹsẹ 1 Iwa ibajẹ koyẹ onigbagbọ ododo ati Imale ododo mo fẹ ki ẹ mọ wipe ọpọlọpọ oni male ati ọpọ ninu onigbagbọ fẹran lati ma ba enia jẹ nitori nwọn fẹ iyin ju iyin Ọlọrun lọ JOHANNU 12 Ẹsẹ 43 iwa ka ri mi ko dara, iwa ki enia yin mi ko dara, iwa buruku bayi pọ lọwọ awọn Onigbagbọ miran ati awọn oni male miran gbogbo ẹyin ọmọ Ọlọrun ati ọmọ Jesu ologbala ẹsa fun ẹṣẹ.


## Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi ailowolọwọ ba nda ọ lamu, biairọmọbi mba ẹ lọkan jẹ, tabi airiṣẹṣe lo nyọọ lẹnu, tabi o tilẹ nṣiṣẹ na owo iṣẹ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiye rẹ ni gbogbo ọna kọna.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ọjọ.

Mọ daju wipe diẹdiẹ lo kọkọ bẹrẹ. Ki o si tun ọna rẹ ṣe. Kọwe pẹlu Ṣile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni ọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunṣe adanwo rẹ lọdọ:-

AWOKAWO
16, MOLẸYẸ STREET
. . BOX 166 YABA - NIGERA

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Itan Onigberaga ati Alaisoto

Lati Ọwọ:- ISIAKA AKINLIYI
Nọ 144 ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Olotu jọwọ gba mi laye lati sọ itan kekere yi fun gbogbo awọn ẹlẹgbẹ mi ati fun awọn onkawe Irohin Imọlẹ, lati le jẹri si ọrọ SINDIKU A. IDOWU Nọ 126 ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye.

Ni igba kan, Ọba kan jọ si ilu kan, osi ni iwa aisotọ ati Igberaga, tara rẹ ni kan lo mọ. Ni ilu kannani ọmọ kekere kanna wa, ti osijẹ talaka pẹlu iwa iteriba ati iṣẹ otitọ si ẹnikẹni. Nigbati oṣe Ọba yi inunibini si ọmọ yi osi le jade ni ilu pẹlu awọn obi rẹ, awọn agba ilu bẹ titi ṣugbọn ofi dandan le lati ṣe ifẹ inu rẹ. Ọmọ yi ati awọn obi rẹ si jade nwọn si lọ tẹdo si ilu kan ti ojina diẹ si ilu Ọba yi, nigbati oto ọdun meji ti o ti nhuwa yi ni ija nla kan wa bẹ silẹ larin ọba yi ati aburo rẹ kan, ti iyẹn sọfun pe afi ki ofi ori oye silẹ fun on, agbara ọba yi ko ka, ni ọba sa jade, oko ti ọmọ yi wa ni osi kọkọ de nwọn si gba laye larin wọn, lai mọ pe ọba ti oṣi awọn ri ipo pada niyẹn, nwọn si nfi gbogbo igba sa agbara wọn lati le tẹ lọrun.

Ni ọjọ kan Ọba yi bere idi ti nwọn fi de bẹ nwọn si sọfun, gbogbo bi nkan na ti ṣelẹ, ati bi oti jẹ pe aimidi ni Ọba le awọn jade, nwọn si rohin fun pe ẹniti oni ibujoko awọn yi ṣnaia dipo, nigbati Oku gbogbo oko ni opin fun awọn, Ọba yi ko le sọ gbangba pe on ni Ọ b a ti o le wọn, oni ti ọ w ọ on ba tẹ iru Ọba na pipa ni on y i o pa, ni awọn yẹn ba sọ fun pe ko to yẹn awọn ti darji ṣe enia jẹ Ọba ko kan ọgbọn, oye ori ni ki ku lailai ni Ọba yi ba gba ẹṣẹ ọmọ yi ma fun idariji ọmọ na si gba, o si pinnu lati ran Ọba yi lọwọ o si gbe apoti kan ti baba on ni sile j a d e o si fi ọwọ gba apoti na ni Omiran kan ba jade ninu re ọmọ yi ba paṣẹ fun pe ki o lọ gbe, ni Ọ b a na ba ni ki ojade ni ilu, ni aburo rẹ na ba jade. Ọba yi ba mu ọmọ yi pada si ilu rẹ o is da gbogbo ikan ini rẹ si meji o si fi ṣe iriju pataki ni nu Ijọba rẹ

Ẹkọ inu itan yi ni pe ko yẹ ki enia ni Igberaga aisoto ati iwa tnu mi ngo ṣe. Olotu modupẹ aye ti ẹ gba mi, Iwaju ni ọpa ẹbiti nre si Iwaju la o mọ lọ o. Amin

## FA OGBON YO

Lati Ọwọ ABDULLAHI AWẸLẸNJẸ

Darukọ Iwaṣẹ ti a fun awọn Ọba wọnyi:-

Apẹrẹ — ỌBA ỌYỌ — ALAFIN

(1) Ọba Ijẹbu - Ode - ỌKẸRẸ.
(2) Ọba Ilu Ọwọ — ỌLỌWỌ
(3 Ọba Ilu Eko — ALAKE
(4) Ọba Ilu Ifẹ — ASẸYIN
(5) Ọba Ilu Ṣhaki — AWUJALẸ
(6) Ọba Ilu Ileṣha - ELEKO
(7) Ọba Ilu Ibadan — ỌNI
(8) Ọba Ilu Ẹpẹ - OLUBADAN
(9) Ọba Ilu Abẹokuta - ỌWA
(10) Ọba Ilu Isẹyin — TIMI

GBANJO! GBANJO!! O MA NLỌ Ọ. GBANJO!!!

A fi eyi kede fun awọn onibara wa jake jado Naijiria ati Ghana pe, a o bẹrẹsi ta awọn ọja gbanjo wa lati ọjọ karun oṣu yi titi di ọjọ keji oṣu to mbọ. (5/3/62 - 2/4/62) nitorina aye wa fun olukuluku ninisiyi lati ri ọja rẹ ra ni ọpọku ọyọku, lẹhin asiko ti a fi sinu iwe yi, awọn ọja na yio pada si iye owo wọn.

Iwe egbogi Ajẹbidan Agbabiẹtu 25/- tẹlẹ di 22/-
Iwe Gbedegbẹyọ Hausa ṣile mẹta 3/ tẹlẹ di 2/-
Iwe Ala ati Iwadi nkan 3/6d di 2/6d
Turari Ajẹbidan fun ẹyọnu ajẹ ati itaja 10/6d di 7/6d
Idaji Pangolo Turari Ajẹbidan 8/6d di 5/6d
Idamẹta 4/6d di 3/-

Fun anfani awọn ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ - Orun Naijiria ẹ wa si ọdọ:-
MANAGER 6, OJO ROAD ODUABỌRẸ MUṢHIN

Wọ Bus Oshodi ki o sọkalẹ ni Bus Stop Muṣhin nibiti nwọn gbe nta Iṣu tutu. Bere Way Street ti o ba tọ ọ de opin, bere 6, Ojo Road, iwọ yio si ri ile iṣẹ wa.
Fun anfani awọn ti o ngbe Eko, lọ si ọdọ:-
LATIFU, 16, BAMGBOṢE STREET LAGOS.

## ITUMO

(1) Awujalẹ (2) Ọlọwọ (3) Eleko (4) Ọni (5) Ọkerẹ (7) Ọwa (7) Olubadan (8) Timi (9) Alake (10) Asẹyin.

EGBOGI

## 'CHILORODONT'




Bere Egbogi Jamani ti o ṣẹṣẹ de fun ẹnu rirun tabi "EHIN ẸNU" ti o ba nyọ tabi kika fun ara rẹ, eyi ni a ma npe ni OMURỌ EHIN Kokoro ni o ma ngbe tabi jẹ idi Eriki na, a si ma jẹ ki ẹnu ma run tabi siwọn bibajẹ pẹlu Pa kokoro buburu yi run patapata nipa lilo egbogi ti wọn npe ni CHILORODONT DROPS.

Igo nla:- Ṣilemeje-abọ pere 7/6
Igo kekere:- Ṣilemẹrin pere 4/
OWO ỌKỌ Ṣilekan-abọ (Postage 1/6d)

BERE FUN

## EGBOGI EKUTE



Ojulowo Egbogi ti o npa EKUTE bi monamọna laini ewu rara fun enia tabi ohun ọsin miran ni ile.

Ṣilemeji pere ni (2/-) Dosini (£1)
OWO ỌKỌ:- Silekan-abọ postage 1/6d
Bere Egbogi wọnyi ni ṣọbu awọn

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

AKIYESI:— Ri daju gbamgba wipe ṣọbu ti wọn nta lo gbe ranṣẹ lọra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọta adamọdi tabi oriṣi omiran fun ọ o, maṣe gba.

## Egbe Nigeria Youth Pioneers se ajodun odun Itunu Awe

EKO:- Ẹnu kọ irohin nigbati awọn ọmọ ẹgbẹ Ọdọ ti a npe ni Nigerian Youth Pioneers ṣe ajọdun ọdun itunu Awẹ ni ọjọ aiku tiṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi ni ita gbangba Isalẹgangan (Ọ ọla) ti wọn si ta ẹni sibẹ.

Gbogbo ẹsẹ ọmọ ẹgbẹ na lo pe ṣọṣọ si ibi ajọdun ọjọ na, nwọn bẹrẹ ijo ni agogo marun abọ irọlẹ, awọn ti wọn yan ni alaga ni Alhadji Lambẹ, Alhaji Laniyan Alhaji S· Yahaya, ati Ọgbẹni L. A. Saidi, gbogbo awọn alaga wọnyi ni wọn fun ẹgbẹ na ni ẹbun owo ti o jọju.

Ọgbẹni M. Odufalu ni o sọrọ nibi ajọdun na, ninu ọrọ rẹ ti o sọ "O wipe ẹgbẹ odọ ni ẹgbẹ Nigerian Youth Pioneers nṣe, gbogbo Ọdọ ti o ba nfẹ Ilọsiwaju ni o le wọ ẹgbẹ na, ẹgbẹ na yio ma ṣe orişirişi ere Idaraya (Sports) ṣugbọn ẹgbẹ na nfẹ iranlọwọ pupọ lọwọ ẹnikẹni ti o ba ni agbara lati ran wọn lọwọ lati fi ra awọn ohun elo ere idaraya na ati ile ẹgbẹ, Ọgbẹni Odufalu na ni o si kọkọ bọ si agbo lati fi ẹsẹ ra ijo diẹ pẹlu Alaga Obinrin.

Oludasilẹ ẹgbẹ na ni Ọgbẹni I. A. Ajumọbi, ninu ọrọ idupẹ rẹ o wipe, Mo ki gbogbo ẹnyin alabaṣe wa inu mi dun pupọ fun wiwa ti ẹ wa si ibi ajọdun wa yi.

Ẹmi gigun ati alafia fun gbogbo wa, Aṣeyi ṣe amọdun Adele ba ire, arina ko ire o, Akọwe Ẹgbẹ na ni Ọgbẹni F. A. Oyerọgba, Ẹgbẹ yio ma roko Amin Aṣẹ.

## To o wo, ki o si ri pe rere ni Oluwa.

Ohun gbogbo ni awọn ọmọde iwoyi npe ni irọ, ṣugbọn ki ẹnikẹni to pe emi ọmọ K a r a ni irọ, a fe ki Oluwa rẹ dan ọ r ọ yi wo, bi bẹni tabi bẹkọ. Ẹnikẹni ti o ba n f ẹ jẹun ti o si ri wipe, onjẹ ti o wa lọwọ on ko ni to on, de ipo ti yio fi yo on, bi ọrọ ba ri gẹgẹ bi a ti wi yi, ki oluwa rẹ to bẹrẹ si jẹ iba onjẹ ti o wa nilẹ na, ki o wi bayi nigba mejẹ fun obinrin ati nigba mẹsan fun ọkunrin wipe:- Bi o joko, o joko arede. Bi o rodo, o rodo apala. Iwọn ẹnu mi lemi gbe kana. Tọ ọ wo, ki o si ri pe rere ni Oluwa.


## FEDERATION OF NIGERIA THIRD DEVELOPMENT LOAN

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £7 million registered Stock in February/March, 1962. The Stocks to be issued will be:-

1. £2 million 5% Federation of Nigeria Third Development Stock 1966 - to be repaid in full on 7th June, 1966.
2. £5 million 6% Federation of Nigeria Third Development Stock 1986 - to be repaid in full on 7th June, 1986

Both Stocks will be issued in multiples of £10 at par, and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the Central Bank during the period 26th February to 26th March 1962.

Prospectuses, which contain full information, and application forms may be obtained from banks or at the Central Bank on or after 26th February, 1962.

*W. A. TIBBLE.*
*General Manager.*

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
FEBRUARY, 1962.


## Bishop Howells da Alufa Dr. Lukas duro

EKO:- Irohin ta siwa leti wipe Olori awọn Alufa ti Ijọ C. M. S. Ọlọla Bishop Howells da Asidikin Dr. Lucas ti iṣe Olori awọn enia Ijọ Bẹrẹfutu duso lẹnu iṣẹ Alufa gẹgẹbi ẹsun ti awọn enia ijọ Bẹrẹfutu kọ ranṣẹ si Olori awọn Alufa wipe awọn ko fẹ ki Dr. Lucas ṣe asiwaju ijọ wọn mọ.

Olori Alufa Bishop Howells wa kọwe si Dr. Lucas wipe, gẹgẹbi iwe ẹsun rẹ ti on rigba lati ọdọ awọn ijọ rẹ pe, awọn ko fe mọ gẹgẹbi Alufa wọn. nitorina on fi aṣẹ on da duro fun igba diẹ titi on yio fi ridi iwadi ọrọ ti on fẹ ṣe. Ṣugbọn a gbọ wipe Dr. Lucas ko ṣe ori kunkun o si da ohun gbogbo, ti o le pa on pẹlu awọn enia ijọ rẹ duro, o wipe Haba! ọrọ kekere ni ọrọ na o kan jẹ ede koyede lasan larin on ati awọn ijọ on.


BERE OJULOWO GBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:—

## RICHALET

FUN ARUN EJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o buruku ti o ba wa ninu "EJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TONIKI Ejẹ ti wọn si nta kakiri ni owo poọku, adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo, Iyẹn ṣe ewọ awa ki ta awọn egbogi bawọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi bawọnyẹn a ma ba ojulowo egbogi atata ti aranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ mo daju pe bi Ejẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wonyi le ṣe ọ Lakuregbe, orişirişi Inarun Ojuşişu tabi didun Jẹdijẹdi Akọ Iba arun ẹdọki Aya didun tanpara ekuru laya.

Ara riro, Lapalapa Egbo ẹsẹ Amodi Apo ile itọ ẹhin didun tabi Ibaradi riro pelu egbogi Risaleti a ma pa gbogbo Kokoro buruku ti o wa ninu Ẹ j ẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu. Ṣa dan Igo rọ kan wo lara rẹ dajudaju iwo yio ma rohin re fun ẹ l o m i r a n pẹlu nigbakugba.

Bere ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878
WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OṢHOGBO.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA